**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbẹ l'orun gbọ. Ẹ o si mo otito, otito yio si sọ nyin di ominira.

# Irohin Yoruba

No. 816 JANUARY 25 — JANUARY 31, 1961 KOBO MEJI (2D)





O dara-pupọ fun Ikọ ti o nyọ awọn ẹbi rẹ lẹnu

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi


# ALHAJI OYEWUSI NI AWỌN ỌMỌLẸBI BASHỌRUN ỌYỌ FẸ KI O JẸ OYE BASHỌRUN



Aworan yi ni ti igbati awon omọlebi Bashorun Ọyọ se ipade nile Olori 'Molebi Bashorun nipa oro oye Bashorun na. Awon olori ẹbi idile mẹtẹta to ni ẹtọ si oye na lo nlo ika si Alhaji Bello Oyewusi to rọgbokun ni-waju wọn.



ALHADJI OYEWUSI

**Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn ẹbi Oloye Bashọrun-Gbenla, Ogunsoro ati Yekanbi ṣe ipade pataki kan or oran Oye Bashọrun Ọyọ, 'Gbakeji Ọba Alayeluwa Ọlọla Bello Gbadegẹṣin Ladigbolu Keji, Alafin Ọyọ. Ki o to to agogo mẹwa owuro ọjọ na ti nwọn fi aseko ipade na si ni ẹsẹ awọn mọlẹbi Bashọrun na ti pe ṣọṣọ si oiude 17. Isale Bashorun, Ọyọ. nwọn fẹrẹ to igba (200) enia**

Lẹhinti Ọgọẹni Lasisi Arẹmu ti ṣe adura fun Alafin Ọyọ. Bashọrun Ọyọ ana ati gbogbo ara Ọyọ tan ni Ọgbẹni Oyebamiji Adio, Olori ẹbi Gbenla idile Bashọrun ti nwọn yan ni alaga wa mu iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi dani o si sọ ohun ti Alafin sọ sinu rẹ si etigbọ wọn nipa oran oye Bashọrun

Alhadji Bello Oyewusi si ṣe alaye ohun ti Alafin sọ gan an sinu iwe na fun won. Ọgbẹni Oyeniyi Akanni Olori ẹbi Ogunṣoro, idile Bashorun si ni on ti gbọ ọ lẹnulọloyi pe, lotito ni nwọn ti sọ ọrọ asọtẹlẹ na pe ẹniti baba rẹ ko ba ti jẹ oye Bashọrun ri ko ni ẹtọ lati jẹ ẹ. O ni Ologbe Oloye J Ọladokun Layọde, Bashọrun ana nikan ni o da asọtẹlẹ na ṣe laifi imọ ati ifẹ ọkan ninu awọn ẹbi Bashọrun si i rara.

Ọgbẹni Oyeleke Alabi, baba Alhadji Oyewusi si sọ pe loni, on ni olori gbogbo idile ẹbi Oloye Bashọrun patapata. O ni irufẹ eto asọtẹlẹ bẹ ẹ ko ṣẹlẹ ri ni Ọyọ, eto na ki i si se asa Yoruba rara.

O ni on ni Oye Bashọrun kan, ṣugbọn on ti darugbo. on si ni on paṣẹ pe, ki Alhadji ọmọ on jẹ ẹ, gbogbo ẹbi si faramọ ọ. O ni nigbati on ti gbe oye na fun ọmọ on ni on ko ṣe kọwe si Ijọba pe on nfẹ lati jẹ ẹ. Apejọ na si sọ pe Alhadji ni o dara fun aye Bashọrun ju Esuọla lọ, ni gbogbo aye.

Alhadji Bello Oyewusi ni, on kọwe na laseko ti nwọn ni ki nwọn kọwe si Ijọba, pe on fẹ jẹ oye na ati pe nigbati Alafin ni ibo ni nwọn yio fi yan Oloye Bashọrun larin on ati Ogbeni Esuọla Akano ni Afin ninu oṣu ti o kọja yi, ibo ti on pọ ju ti Akano lọ. Ọgbẹni Oyebamiji Adio si danimọran pe ki awọn kọ iwe ẹbẹ si Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ki o maṣe ka ọrọ asọtẹlẹ na ti Oloye Bashọrun ana sọ kun, ki o si fi Alhadji Bello Oyewusi jẹ oye Basnọrun laipẹ ọjọ. nwọn si kọ iwe na, awọn olori ẹbi si fi ọwọ si i.

Awọn ara adugbo Isalẹ Bashọrun tun sọ pe Alhadji Oyewusi ni awọn nfẹ, awọn yio si lọ sọ ifẹ awọn fun Alafin, ninu ọsẹ yi. Nitorina bi nwọn ba si ti tun sọ ọrọ oye Bashọrun Ọyọ na si, ẹ o ma a gbọ o.

## Ijoba Ipinlẹ Iwọ-Orun yio ta orire lọjọ Ẹti

IBADAN.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹta-dinlọgbọn oṣu yi ni Gbọngan Apesi Mapo ni Ijọba yio ta Orire kẹrinle-logun lati mọ awọn ẹniti o ṣe orire jẹ owo. Lati agogo mẹjọ owurọ ọjọ na ni nwọn yio si ti bẹrẹsi ta a.

## Atọka

### Wo


Akibu Alarape 4
Akede Ọna gbala 5
Itan iṣẹdalẹ lu Ara lẹ ba Ẹdẹ 7
Alapara Ibadan 10
Ọrọ Evangelist Akande 12
Akiyesi awo irawo nipa ọjọ-ibi 15

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Ọwa Igbajọ ṣe ajọdun kẹta

IGBAJỌ.

AWỌN enia ja-nkan ja-kan lo wa sibi aşeyẹ ajọdun kẹta ti Ọba Alaiyeluwa Adelani Famokun Keji, Ọwa Igbajọ ṣe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogun oşu kejila ọdun to koja fun ajọyọ ọdun kẹta ti o ti gun ori oye.

Ni ọjọ Abamẹta ti i ṣe ọjọ kẹtadinlogun oşu kanna ni Ọba na ti bẹrẹsi inawo Nwọn bẹrẹ ere aisun ni Afin rẹ ni deede agogo mẹwa alẹ, nwọn si ṣe ere na titi di ilẹmọ ọjọ keji.

Ni owurọ ọjọ keji, Ọwa ati awọn ara ilu, awọn alabaşẹyẹ lọ se isin idupẹ ni Ṣọọşi awọn Onitẹbomi (Baptist Church, Igbajọ). Alufa J. A. Ebo lo si ṣe akanşe iwasu ọjọ na. O ṣe adura pe ki alafia ati ibukun Ọlọrun ma a ba Ọwa ati awọn ara ilu gbe. O ki i ku aşeyẹ, o si tun ṣe adura fun awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Naijiria pẹlu.

Ni ọjọ na, Ọwa fi oye da awọn mẹta lọla. Awọn ni Ọgbẹni J. Ade. Oroge (Jigun), E. F. Lorẹmikan (Logunode) ati J. Afọlabi Mojaro (Logun Lokiran).

Ki ade o pẹ lori, ki bata o pẹ lẹsẹ.

## Isinku Oloye Ọdọfin dun

ODE-IRELE.

ESẸ awọn ọmọ Egbẹ Afẹnifẹre lo pe sibi isinku Oloye Ọdọfin Adefunwa ni ọjọ Ọjọbọ ti i şe ọjọ kọkandilọgbọn oşu keji ọdun ti o koja (1960) ni Ode-Irele.

Lati owurọ ọjọ na ni awọn enia ti pe si ile ologbe Oloye na, awọn ọmọ olọku si nawo pupọ. Nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaşẹyẹ isinku na lọrun.

## Ẹgbẹ Ọdọ Ipetu Ijẹsha ṣe ipade alarinrin

IPẸTU-IJẸSHA.

IROHIN ko to afojuba ni ti aşeyẹ ipade ajọdun kini ti awọn ọmọ Egbẹ Odo Ipẹtu Ijẹsha (Ipetu Ijesha Boys' and Girls' Association) şe ni ile iwe "St. Paul". Ipẹtu Ijẹsha ni ọjọ Aje ti i şe ọjọ keji oşu yi.

Ọgbẹni Michael Ọgbayun, ti i şe Baba-ẹgbẹ na ni o şe alaga ipade na. O si şe aye na dada.

Ipade na bẹrẹ ni deede agogo mẹwa abọ owurọ pẹlu adura. Lẹhinna ni alaga sọrọ iwur., o si sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ona ti o yẹ ki nwọn o ma a gba. O fi awọn ilu orişirişi apẹrẹ, o si te ẹ mọ won leti pe ko si ohun ti o ga ju ifẹ ati irẹpọ lọ. O si tun sọ fun wọn pe nwọn ni lati ma a ni itara si ohun rere larin ilu.

Lẹhin ọrọ alaga, awọn ẹka ẹgbẹ na ka irohin won lọkọọkan. Alaga kan saara si awọn ẹka ẹgbẹ ti Ipẹtu, Ibadan ati Eko fun nkan ribiribi ti nwọn ti se ati eyiti nwọn dawole fun ilọsiwaju ilu wọn. Bi alaga ti sọ oro re tan ni akowe ẹgbẹ ka ofin odun titun. Lẹhinna ni nwọn yan awọn Oloye.

Ni irọle ọjọ na, awọn ọmọ ẹgbẹ na bẹrẹ ere alarinrin, nwọn jẹ, nwọn si mu.

A şeyi şamọdun o.

## Aşaolu jẹ oye Egosi Ilọffa

EGOSI ILỌFFA-ILỌRIN.

AWỌN Oloye Afọbajẹ fi Ọmọ-ọba A. Aşaoku jẹ Ọba Egosi Ilọffa lẹnulọlọyi. Esẹ awọn Oloye, saraki ati awọn ẹgbẹ orişirişi lo pe si ibi aşeyẹ na. Awọn Egbẹ Atunluşe şe inawo pupọ lọjọ na. Gbogbo awọn alabaşẹyẹ ọjọ na jẹ onjẹ orişirişi, nwọn si mu orişirişi ọti pẹlu.

Iro ibọn bẹrẹsi dun lọtun losi.

Awọn Oloye Elemọ, Oloye Oke-Ọwa, Oloye Okorun ati Oloye Petu-Onigẹmọ mu aşeyẹ ọjọ na dun pupọ.

Ki ade pẹ lori, ki bata pẹ lẹsẹ o.



# Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣi ile ẹrọ ina lẹntiriki si Ilaro







ILARO.

N[1] [illegible] ... Minisita Alamojuto [illegible] ... Ọlọye A. O. [illegible]




# Awọn mẹtala jẹ oye ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ajegunlẹ Ọtta

AJEGUNLE.

O[illegible] ... Ajegunle Ọtta ... [illegible]

Ọti orombo ti o gbamuṣe



# ALAPARA IBADAN PADE ALAWADA EKO

ALAPARA—Olotu, ẹ ku owurọ o, ẹ ku iṣẹ o, ajinde ara yio ma a jẹ nyin o.

OLOTU—Alapara, ma a wole. Ẹ ku ọjọ mẹta. Ẹ de ku aṣeye ti Ẹyọ. Ṣe ara ti le dada nisisiyi?

ALAPARA—Ẹ ṣeun, mo dupẹ pupọ. Ara ti le dada, mo si ti ngbadun.

OLOTU—Alapara, o tilẹ mo irin rẹ na rin, njẹ o mọ ẹniti o joko lọdọ mi yi?

ALAPARA—Nko mọ o. Mo juba o, alagba, ṣe alafia ni ''le wa?

OLOTU—Ẹniti o nki yi ni ọkan ninu awọn onkawe "Irohin Yoruba" wa, o si jẹ eni-pataki. Omoluabi bi iwọ na ni i se. Orukọ rẹ a si ma a jẹ Alawada Eko. Ko pẹ pupọ ti on na de ọdọ mi ni iwọ na de yi. Ọrọ re ni o si nso lọwọ. Alawada, Ọgbẹni wa Alapara Ibadan ti o fẹ lati mọ na ni o mọ lojukoju yi o, ẹ ki yio ha ki ara nyin, ki ẹ si fi ọrọ jomitoro ọrọ?

ALAPARA:—Mo ti juba lẹkan, mo tun juba lẹkan si i.

ALAWADA—O ṣeun Ọgbẹni Alapara, mo ti ngburo rẹ ti pẹ, inu mi si dun lati ri ọ l'owurọ yi. Mo ti lọ si ibikan bi mo si ti de ko pẹ pupọ. Bi mo ti de na ni mo bẹrẹ si ka awọn iwe "Irohin Yoruba" ti gbogbo ọsẹ ti nko i ti ka tẹlẹ. L'owurọ yi ni mo ka ti ọsẹ ti o koja. Nigbati mo ka nipa bi o ti ṣe wa woran Ẹyọ ti nwọn ṣe l'Eko ninu osu yi, a ti bi nwon ti ṣe fi ọpanbata ki ọ dada, gbogbo rẹ ni mo ka. Pẹlẹ ọjọ, ṣe ọpanbata na ko kọ ila si o lara?

ALAPARA—Mo dupẹ pupọ, Ọgbẹni Alawada. Mo woran Ẹyọ, mo si ri nkan wo. Iyẹn ti wa, o si ti lọ, ere miran ni ki a tun ma a reti.

ALAWADA—Mo gbọ pe nwọn yio tun ṣe ere Ẹyọ miran ninu ọdun yi, emi yio ba wọn ṣe e lagbara Olorun,ki o si to o to igbana, ngo jẹ ki Olotu o sọ fun ọ, ki o wa woran. Ngo si fi ọ mọ awo, bi o ba fẹ.

ALAPARA—Awo kini?

ALAWADA—Mu suuru, ki ọjọ na ku saata,ngo jẹ ki o mọ, eyiti o ba si fẹ ṣe nibẹ ki o sọ fun Olotu. Bo ti le jẹ ti Ẹyọ na ni, etiṣe, ṣe bi ọkunrin ni ọ, tabi ojo enia ni ọ ni?

ALAPARA—Ki i ṣe ti ojo. Wahala ere Ẹyọ pọ pupọ. Inawo rẹ si pọ. Ti owo nina tilẹ kọ, ewo ni ki a ma a ṣe ere ki a si ma a lu ọpa. Mo mọ ẹnu pe ki a jẹ, ki a mu, to ba de ibi ti ki a ma a bara ẹni ni ọpanbata, emi ko le e ṣe iyẹn.

ALAWADA—Olotu, nko ro pe Ọgbẹni Alapara yi nṣe ọkunrin. Ojo enia ni. Kiliṣe ti o fi mbẹru to bayi? Kini wa ninu ere Ẹyọ ti o to nkan ti enia yio ma a fi bẹru rẹ to bayi? Alapara, o ma ya mi lẹnu fun ẹ o. Bi nwon ba sọ pe o jẹ ojo enia bayi, ti o ko ba si nibẹ, nki ba ti gbagbọ!

ALAPARA—Ọrọ ojo kọ ni ọrọ ki a ma lu ara wa ni ọpanbata. Ere Ẹyọ ki i ṣe ere ọmode, agbalagba ti ko ba ni aiya rẹ ko gbodọ tilẹ ba won ṣe e, paapa bi o ba jẹ ti o ni 'Hu-ha-ha' ni, emi ko si nibẹ. Nko le fi arugbo ara [illegible] gẹlẹdẹ.

ALAWADA—Olotu, e gbo nkan ti Ọgbẹni Alapara nso. O ko le fi arugbo ara jọ ijo gẹlẹdẹ, tabi kilo ti wi? Njẹ ere Ẹyọ ati ọdun Oke 'Badan, tabi ọdun Oloolu ati ere Alapaṣanpa, ewo lo roro ju? Tabi



ALAPARA IBADAN

o ko si nilu nigbati nwọn ba nṣe awọn ọdun wọnyi ni Ibadan ni? Mo sa ti gbe Ibadan ri, gbogbo ere wọnyi ni mo si ti fi oju mi ri, ko si eyiti ko roro ju ere Ẹyọ lọ ninu wọn. Nitootọ, ere Ẹyọ ere owo ni, ṣugbọn bi inawo rẹ ti to bẹẹni igbadun ati ẹyẹ rẹ to. Gẹgẹbi Olotu ti wi fun ọ lọsẹ ti o kọja, ti mo si ka a ninu iwe "Irohin Yoruba", nwọn ki iṣe ere Ẹyọ lasan. O wa fun ẹyẹ ati iranti awọn nkan ati enia pataki nilu ni. Ere Ẹyọ ki ṣe ere ti awọn enia yio bọ ara wọn si ihoho, ti nwọn yio ma a ṣe bi awọn onibori bi ti gambari Alapara, mo fẹ ki o mọ nipa ere Ẹyọ dada ki o to le sọ bi ere na ti ri. Olotu, o ṣe mi lanu pe mo fẹ tete ma a lọ, ọna mi pọ l'owurọ yi, mo fẹ de Apapa Elẹmu, ti mo ba si kuro nibẹ ngo de Apapa Elẹkọ nelu, ki nio dari wale. Ngo tun de ọdọ nyin titi ọjọ mẹta. Ẹ ṣeun, ẹ ku atijọ, 'ajinde ara yio ma a jẹ.

ALAPARA—Ọgbẹni Alawada, o ṣeun pupọ, mo gbọ gbogbo nkan ti o sọ nipa awọn ere ọdun wa, anu ṣe mi pe o ko le duro ki nfun o lesi, a o tun ma a ri.ara wa.

OLOTU—Alawada, mo gbọ nkan ti o wi, o ṣeun, o digba, oju yio tun ra ri o, Awe. Alapara, lọjọ wo lo tun da, tabi iwọ na nlọ si...

ALAPARA—Lọ sibo? Mo nlọ sile mi ni. Ngo tun de ọdọ nyin titi ọjọ mẹta. Oju ko fẹra ku o.

OLOTU—O digba.


## Ran awọn eree lọwọ Da ẹhin didun duro

[illegible]

**Cystex**

CYSTEX [illegible] fun Eree (kidney), Lakuregbe, [illegible]





# Ẹka Ẹgbẹ ọmọ Oduduwa Mushin se ase apejẹ

MUSHIN.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtadilogun oṣu ti o koja yi ni Eka Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa Mushin pe ipade apejẹ kan si ile Ọgbẹni J A. Ọnasanya, 'Gbakeji Akọwe ẹgbẹ na ni nọmba 7, Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin lati fi ki awọn Ikọ ẹgbẹ wọn ti o lọ ba awọn Apapọ Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ṣe ipade ajọdun kẹtala ti nwọn ṣe ni Ibadan laipẹ yi.

Nwọn pe awọn Oloye Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Mushin meji, Ọgbẹni Paul O. Ogunade, Akapo ati Ọgbẹni Popoọla Adegun ('Yes I know') Akọwe sibẹ, inu awọn mejeji na si dun lati d oruko silẹ fun wiwọ Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa lẹhin ti awọn Ikọ Ẹgbẹ na j'abọ tan.

Awọn Ikọ na ni Oloye V. A. Cole ati awọn Ọgbẹni J. A. Ọnasanya, M. T. Ṣolaja, R. Adeṣina, E. A. Bakare ati Alade Buari Irohin ti awọn Ikọ na si mu bọ ibi ipade Ibadan ti nwọn lọ na fun gbogbo enia ni iwuri ati pe, owo ti nwọn da ninu ipade na pa-bambari, Ọgbẹni A. O. Adeṣẹgun si wa ninu ipade ase apejẹ na pẹlu.

Aṣeyi-ṣamọdun, ajọitu ẹgbẹ o.

# Akọwe-Agba Ẹgbẹ Alakukọ ni Igbajọ wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

IGBAJỌ-IBADAN.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu kini odun yi ni Ọgbẹni James A. Kọlarin ti iṣe akọwe-agba fun Eka Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) Igbajọ, Ibadan fi ẹgbẹ na silẹ, o si wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) pẹlu ogunlọgọ awọn ọmọ ẹhin rẹ.

Nwọn ni ohun ti o mu awọn fi Ẹgbẹ Alakukọ silẹ ni pe adagbamaleṣe ni wọn, ẹnu lasan ni nwọn lo, ati pe gbogbo ohun ti nwọn ni awọn yio ṣe fun idagbasoke ilu Igbajọ, nwọn ko ṣe e. Nwọn ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre nikan ni o nṣe ileri ti o si le mu u ṣẹ.

Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun kọ Ile-ibimọ-si (maternity centre) si arin ilu Igbajọ ki awọn obinrin ba le ma a bimọ ni irọwọ-irọsẹ, nwọn ṣe ẹrọ redio si arin ilu ki awọn ara ilu ba a ni anfani lati ma a gbọ irohin lati okere, nwọn si tun yọ oda si titi ilu.

Bi Ọgbẹni Kọlarin ti nsọrọ aponle nipa awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni awọn enia rẹ paapa bẹrẹsi yombo Awo! Awo!! Awo!!!

Ọkan ninu awọn igi lẹhin ọgba Ẹgbẹ Alakukọ ti oruko rẹ njẹ M. S. Ọtta paapa fi ẹgbẹ na silẹ o si w'ẹgbẹ Afẹnifẹre pẹlu.


Ẹ ma a ka Iwe

IROHIN YORUBA

nigbagbogbo fun irohin aladun


# ITAN OṢUPA [3]

*( Lati ọwọ S. L. Ogunniran, Ibadan )*

OBIRIN a ma a rin irin igberaga, a ma di irun igberaga, a ma a wọ ẹwu faari, a kun atike ijọngbọn, on a si ma a ro aṣọ "kopemikolo." igbati obirin ba fẹ lọ sode, on a we gele arage; a wọ ẹwu afẹaiye pẹlu bata idẹ. Gbogbo nkan ọṣọ ara ti awọn iya nla wa ko lo ri ni on yio ko jade nile, gbogbo eyi ti nwọn si nta lọja ni yio jẹ dukia pataki fun un.

Nigbati o ba bọsi opopo ọna, bi o ba ti ri ọkunrin ni ọkankan, a pa irin ẹsẹ re da, a si ma a wọ bata nilẹ gerẹrẹ-gerẹrẹ. A! iwọ obinrin' kini afẹfẹyẹyẹ yi jasi? Aṣọ ti o wọ yi yio di ogbo, ẹwa tio fi ntan awọn enia yio ṣa, gbogbo ohun ti o gbojule yio si di ofo. Wo ẹhin wo, awọn ayaba atijọ da Ṣebi iku ni o mu gbogbo wọn lọ?

**IBANUJẸ**

A! ko si ẹniti igbe ifẹ obinrin le ọkan aiya ti oluwarẹ ki yio kan ibi ninu rẹ bi o ti wu ki o mọ, nitori ko si ohun ti o rọmọ ifẹ obinrin ti o ju ibanujẹ, a fi Ọlọrun Ọba ni o le gba ni lọwọ wọn. Ifẹ obinrin buru, ko ni gbongbo, bẹ ẹ ni ko ni ewe, sibẹ, on a ma a taka inu ọkunrin bi iṣu.

Ko si ẹniti o le sọ ibiti agbara ifẹ obinrin wa nitoripe o jẹ ibi airi, bẹni ọmọ enia ko si le sọ nipa agbara ti o fi ndari ọkunrin. Ifẹ obinrin a ma a mu ni dagba le ohun ti a ko to iṣe, on kanna ni isi mu ni ru ofin Ọlọrun Ọba. Melo ni o si ti di ẹpọko-esin nitori obinrin?

Ọpọlọpọ ọkunrin ni o ti fi ẹnu kọle ti o si ti fi ẹnu ra mọto nitori ọran ifẹ, ogunlọgọ ni o si ti ṣe ileri ofo nitori ifẹ obinrin. Ibi nyi lu ibi, ẹsẹ nyi lu ẹsẹ, bẹ ẹ ni iku gbigbona si npa ọmọ araiye nitori obinrin.

(KOI TI PARI)


PALM LINE

wa fun iṣẹ rẹ



Fun kiko oriṣiriṣe ọja wọlu ti enia ni lati ma a lo lojojumọ lọ si idi irinṣẹ ohun ọgbin ati ti ẹrọ, awọn ọkọ Palm Line titun ni o yaaju fun iru iṣẹ bẹẹ nipa titete ṣee ati ọlẹe dada nigbakugba. Erukẹru ti o ba ti ni fifi ọkọ ko Palm Line ni gbogbo irinṣẹ ti o yẹ fun un, – o si wa fun iṣẹ rẹ nigbakugba.

Iṣẹ wa ni lati ma a ko gbogbo ẹru nyin

Koowa fun PALM LINE

# Awọn Owe ilẹ Yoruba

OWE l'eşin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu owe ni awọn baba wa fi nwa a l'aiye atijọ. Bẹ ẹ si ni l'aiye isisiyi. Owe jẹ amọna, o si nfun ni ni laakaye dara-dara. Ẹ kiyesi ẹniti o ba mọ owe, bi ọrọ ti le wu ki o dikoko to, yio mọ idasi ati idajọ rẹ, yio mọ ọ tu, yio si mo ọ ba, yio mọ a ti şa nkan si ara wọn dara-dara. Wọnyi ni diẹ ninu awọn owe ilẹ Yoruba. na:

Aguntan nşe iyawo, agbo gba ilu s'ẹhin, pẹpẹiyẹ mu şokoto, o ni "nwọn yio mọ mi ni ilu yi loni". Kila ti ki ! kan won?

A ki i şẹgi ninu igbo ki a ma fi oran ro ara ẹni wo.

Ajumọbi ko kañ t'anu, ẹniti Oluwa ba ran si ni ni 'ise ni loore.

Eni aigbọn pa lo pọ, ẹniti ogbọn pa ko to nkan.

Eniti a ba jẹ l'eşi ko si mọ, ẹniti aiye ba ri l'aiye mbajẹ.

Eni ba f'ipọnju kọ 'yin a kọ abọn, ẹni ba f'ipọnju rojọ rẹ a jẹbi Ọba, ẹni f'iuọnju lọ gbẹ ibo a gbẹ ti aworiwo.

Iwosi ọkọ ero, a ko ri ibi gbadun; ina tun nje ni kikan-kikan.

Igba aberẹ nwọn ko to ọkọ, igba irawọ nwọn ko to oşu, igba oşupa ko le jọ ọsan, igba orore ko t'ọkan aparo, igba ekute-ile, nwọn ko to 'Tu, igba adiẹ ko to ẹran-nla, igba ẹtu ko to erin, igba eşu nwọn ko to adiẹ.

Igi ki i da l'oko, ko pa ara ile.

Igba agbado ti kuta lọja, ti jero wa ni ki nwọn dan on wo na; kini ọka baba tun ma a wa wi?

Ka ma r'ẹjẹ, ka ma r'ẹjẹ Turuku nf'itan dina larin ilu.

Kannakanna de ilu tai delu, o nke "mahawọ", panla melo lo ba nidi awọn ẹgbẹ rẹ.

Ka ba le pẹ nibẹ, abuke ni bi on ba ku ẹhin ni ki nwọn gba tu ifun on.

Ojo to rọ lo da ẹrẹ silẹ.

Ọmọde jogun ilu o nyọ şẹşẹ, ko mọ p'aimọ ọ lu l'o pa baba on.

Tanit'ọlọrun ki işe aja kaja Ekun lo da a mu rẹ.

Adun kini mbẹ l'ara orogbo; a pa a ko l''awẹ, a jẹ ẹ o koro, a da a o di!

Apọn sọ ọbẹ di eegun, eyiti o ba sọ pe "baba ma wo'lẹ" o ni "baba ma a wo ọbẹ".

A ki i le adẹtẹ s'ẹhin odi ki a tun ma a gba ohun owọ rẹ şe alejo, bi ori rẹ ko ba bi ni Odumare yio bere!

A-mọ-rewọ alugbẹdu Ilaga: o ni bi on ba nñ owọ lu ilu, on le ma a fi ori ati ẹsẹ jo; on kanna a tun ma a darin si i.

Bọkini on ọlọrọ ẹgbera obun on aşiwere ọkanwun; ọkanjuwa on ole deede ni nwọn jasi.

Dide lo de gbese abijọ: o yan guguru o kun ile, o pọnmi ta o digbese, o se asaro (ẹbẹ) gbaguda o padanu, o lọ ki ọlọfọ o tẹ ẹ lọmọ pa, ẹniti o nsure bọ lati mọ ọ da ni itan, eyiti o ni ha! ẹnu rẹ ya.

Enia ti iba ş'ẹgbẹ rẹ nika, Ọlọrun Ọba ki i jẹ ko nipa.

Gbogbo ọran ni i şoju eke, ibi gbogbo l'olẹ wa.

Suru baba iwa, agba to ni suru ohun gbogbo loni.

Ipilẹşẹ lo l'oke.

Oju-ko-rọla-ri ni i şọmọ rẹ ni ọlaniyọnu.

Ọmọran bere ọran wo, ajapa (awun) ni ẹniti nwọn pa jana ka a ku tan?

Oga ni aayan, ẹwu kafutani mẹfa ni on nikan ni, alantakun ti o nñ ojojumọ ran owu ko ni ẹyọ ẹwu kan.

Bi a ngbe ẹkun yi ẹrẹ, ki i şe ẹgbẹ ewurẹ.

Oga ni afeku—komọ, ẹnikan ki iri itan iru ninu işasun

Agba ni ẹtu, ẹiyẹ-oko melo ni o huwo?

Ẹniti o sọ oko lu agbọnrin şe aajo ọbẹ, eran ni ko ku.

Alabahun ni inu on ko dara, ñwọn ni ko purọ, ẹniti o ba ti ri ẹhin rẹ ti mọ.

Bi nwọn ba nyọ ilẹ i da, ohun wẹrẹwẹrẹ a ma a yọ wọn şe.

Nko ni şaigba owo mi lara aşọ yi, were rñ nsọ wọn da.

Adiẹ jẹun tan, o mumi tan, o ni, o ma şe o, ñile-hiniẹnu ni o njẹ on ni iya bayi! Kini o tun ku ti awọn ti o lehin-lẹnu tun nşe?

Oekan nihin, eeji lọhun, ni oja fi nkun.

Bi ọla ba ti ntan, a ma a wu wọn, bi ọla ba soju-de, a su won.

Enia buruku pọ nwọn ju igbẹ lọ, ẹni rere han ju omi-oju lọ.

Adẹbọ-rubọ ni ẹiyẹle fi nye ẹyin rẹ sinu ile, adẹbọ-rirubọ ni adaba fi nye ẹyin tirẹ sinu igbẹ.

A-ri-eyi-ri ni ti onile, a ko ri-ẹyi-ri ni ti alejo, bi onile ba sọ pe k ia jẹ ẹ tan, alejo a sọ pe ki a jẹ ẹ ku.

Arisiki ẹşin, inu ile ni o mba a, malu ni o nwa tirẹ kakiri arin igbẹ.

Aiye ni akọ-alangba ba agilinti, ki o to da ẹwu ẹtu pẹlu fila aburo.

Aguntan ti o mba aja rin yio jẹ igbẹ.

Aworawọ ko kan ti işẹ, [illegible] şailọ.

Awodi iba ku, aladiẹ ko sunkun, bi a ba şubu ọmọ-araiye a ma a rin ni.


# Mu OVALTINE lojojumọ!



Mu OVALTINE larọ fun agbara jalẹ gbogbo ọjọ.

Mu OVALTINE sun lalẹ lati fi ara rẹ si eto nigbati o ba sun.




OVALTINE — Onjẹ Atata — ti o jẹ nkan Mimu

Otutu fẹrẹ ti fun un ni "K.O.!"





MENTHOLATUM CO. LTD
(Est. 1889), Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARAJU

# Itan Iṣẹdalẹ ilu Ara lẹba Ẹdẹ

(Lati oju ewe keje)

run; (14) Joseph Amọọ, Osi; (15) Daniel Amuṣan, Ṣọbaloju; (16) Zaccheus Ajibọde, Oluọdẹ; (17) Olori ẹmolẹbi Isaac Adewale Alao, Baba-isalẹ.

**AWỌN ORIKI**

Oriki Ọba Oduṣina lọ bayi.

"Onikẹpe, Bamgboye, Eegun kekere ko ṣe e di lokun, Eegun wọnu aṣọ, ṣ'ẹku gbọọrọ-gbọọrọ. O daṣọ pempe, a ni o nsolẹ, o daṣọ gbọọrọ-gbọọrọ, a ni o nain eegun jẹ. Eegun wọnu aṣọ labu gbọọrọ-gbọọrọ ọkọ ayaba. Enikikun ni o mọ ibiti nwọn nlọ, ẹlẹwu-ara ni i mọ ibiti a nre. Ọba gba mi-gba mi, ngo r'Ejigbo, bọya, ma de 'Lobu, ọkọ Awemọla, ọkọ Otuṣẹgi, ki i r'alejo Baba Iṣẹ-ori-ran. A to o ti bi awọ, ki i ta ara rẹ lọpọ, gbogbo ọwọ ni i fi i konimora."

Oriki Ọba Ilufaye si lọ bayi:—

"Tẹwọgbade, Ilufoye, a ko janin-janin bi ẹlẹmu ọkọ Oniwinde, Apesin bi oke-Ibadan Tẹwọgbade Ilufoye baba, Ọwọade, Ataiyeṣe bi Olubi, Ọdundun ọmọ asodedẹrọ, Alao ọmọ Shangorẹmilẹkun, Tẹwọgbade ọmọ Abidogun, Ọba ti nṣ'ọrọ to tun nṣe'gungun, Ilufoye Alao ti nṣe onigbagbọ ti o tun nṣe 'male, Abudu Salami, Abudu Bakare, Lakisokun, Ajẹ ni i mu'le gbona girigiri, Ọba to, to, to."

Oriki Daddy Isaac Adewale Alao, Olori Molẹbi Ara lọ bayi:—

"Babasalẹ ko binu ẹnikan, ọjọ gbogbo bi ọdun ko binu ẹnikan, ọkọ Aderoju, afinju Onigbagbọ ti i daṣọ suru bora, ọmọ Fikuyẹmi, ọjọ gbogbo bi ọdun, Babasalẹ ko binu ẹnikan."



DA

INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, okun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe ọmiro ti pọju nibẹ. Ọmiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya.
Ṣa ti mu egbogi Phillip's 'Milk of Magnesia' diẹ ........yio si ko rirogun omirọ na kuro, a si le irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.
Ko lewu, o rọrun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'

Awọn ti o nṣe e ni

PHILLIPS

ODARA FUN GBOGBO ẸBI



KOKORO AWỌ - ARA

le ba ere idaraya rẹ jẹ





ṣe iranlọwọ lati fi ọṣẹ Asepso ṣe atako wọn

Kokoro awọ-ara ki lse nigbagbogbo nikan, nwọn ko dara lati ma a wo. Eyi ni o fa a ti ẹniti o ba mba ja fi ngni ipalya, nwon ko si ngni arisiki to bi iba ti to. Ma jẹki ara alan ati iṣaka ba aiye rẹ jẹ. Pana kokoro-ara na ki o to yoju nipa lilo ọṣẹ ASEPSO. ASEPSO ni egbogi apakokoro ti o lagbara nina. Ki lṣe pe fun awọmọ nikan, ṣugbọn fun pipa run awọn kokoro ara rẹ ki o ma le yoju.





Tọju awọ-ara rẹ ki o mọ, ki o si bọ lọwọ arun nipa lilo ọṣẹ Asepso deede

X-A 36/321 0041-60

# Agbaje ati ọọdun enia kuro ninu Ẹgbẹ Alakukọ wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

NNU ọsẹ ti o kọja yi ni Oloye Joshua Agbaje, okan ninu awọn ti nṣe aṣoju ninu Igbimọ ijọba ibilẹ iha Gusu ilesha ti o ti fi igbakan wa ninu Ẹgbẹ Alakukọ (N C N C) fi ẹgbẹ na silẹ wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group)

O ni o ti di ọdun kẹwa ti on ti wa ninu Ẹgbẹ Alakukọ na ti on si ti nfi gbogbo ara on ṣiṣẹ fun ẹgbẹ na ṣugbọn asẹhinwa-asẹhinbọ on ri i gbangba pe, ẹgbẹ na fẹran lati ma a tan enia jẹ. on si k'abamọ nipa rẹ.

Oloye Agbaje sọ pe bi o ba ṣe pe ọdun mẹwa ti on fi sin Ẹgbẹ Alakukọ yi. Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni on fi ṣiṣẹ fun ni, iṣẹ iṣelu on iba ti mu ere wa yatọ si adanu yi. Awọn ọmọlẹhin rẹ ti o si ba a fi Ẹgbẹ Alakukọ silẹ wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre jẹ ọọdun (300) enia.

## Ijọmeje Aiyeraiye ṣe ajodun ikore

ILE-IFẸ.

IJỌMEJE Aiyeraiye ṣe ajọdun Ikore wọn l'adugbo Abewela, Iremọ, Ile-Ifẹ lenu lọlọyi. Ẹni-ọwọ O. O. Fawole ti o ṣe Alaga ni o ṣe akanṣe isin, awọn ọmọ ileiwe Oke-Mẹsi si ka ẹkọ. Awọn Ọgbẹni Daniel Adewọyin ati Ezekiel Ọla ti nwọn wa fun ajọdun na lati Mẹsi Ọlọja-Oke ṣe wasu.

Lẹhin eyi ni gbogbo awọn alajọdun na korin aladun, bi nwọn si ti nkọ orin ni nwọn njo.


NJẸ O NI OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA



## Ojo mba Basikulu rẹ jẹ!




JOHNSON'S
NU-CYCLE

REG HARRIS—Ọjọgbọn ọga awọn asare-ije basikulu gbogbo aiye fun ọdun mẹrin—sọ wipe:—
Asẹhinwa-asẹhinbọ, ohun-elo kan niyi, lati fi nu, lati fi dan, ati lati fi daabo bo basikulu—
JOHNSON'S NU-CYCLE ko ni mu ẹnu basikulu rẹ gun nikan, sugbọn yio tun daabo bo ara rẹ ati ẹwa rẹ pẹlu, nitoripe o ndaabo bo ise ọda ati irin-didan rẹ kuro lọwọ erukuru ati jijẹ-irin ati fifaya. Tele apejuwe mi—
Ma a fi ori-adanrin JOHNSON'S NU-CYCLE nu basikulu rẹ deede losoose ki o si ri iyato na." Ma a fi basikulu rẹ yangan nipa lilo JOHNSON'S NU- CYCLE




a product of JOHNSON'S WAX research


Published by Allied newspapers Limited Elephant House 214, Broad Street Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited Fun owo "IROHIN YORUBA" odun kan -Ṣko sile mejo ati ẹobo mejọ (8/8d.) Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S M. Ademuyiwa, 2 Idumagbo Street Odi-Olowo Mushin